Bibeli fun awon omode

# Jesu ati Lasaru



Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Janie Forest
Alastair Paterson

Olu'lo: Ruth Klassen

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi, niwon igba ti o ko so di owo.

Maria ati Marta ni aibale okan nitori lasaru arakunrin won n se aisan, awon arabinrin re mo pe Lasaru le ku laipe won ranse si Jesu ti O nifee ebi yii lati Betani wa.



Nigba ti Jesu gbo nipa Lasaru O so fun awon omo eyin pe “aisan yii ki se si iku” Bi o tile je pe Jesu wa ni ona jijin O si mo ohun ti yoo sele si Lasaru.



Jesu duro ojo meji si i ki o to kuro ni Betani Nigba naa O wi ohun nnkan ti o ru awon omo eyin loju pe "Lasaru ku. Inu mi dun nitori emi ko si nibe ki eyin le gbagbo" kin ni oro wonyi tumo si? Kin ni Jesu n gbero lati se?





Nigba
ti Jesu de
Betani o ti di ojo
kerin ti Lasaru ti
ku won ti fi aso
we e oku re won
si te e sinu iboji.

Marta jade lo pade Jesu "Arakunrin re yoo jinde pada Jesu wi fun un" "mo mo pe ni ajinde nigbeyin ojo." Marta dahun. O ro pe Oun o duro di akoko ajinde ki oun to ri lasaru pada." Sugbon Ohun ti Jesu n so yato.





“Emi ni ajinde ati Iye” ni Jesu so fun Marta, “eni ti o ba gba mi gbo bi o tile ku yoo ye” Marta gba Jesu gbo. O mo pe Oun (Jesu) ni omo Olorun Sugbon bawo ni o se le ran Lasaru lowo?

O je ibanuje fun gbogbo eniyan nitori pe Lasaru ti ku. Arabinrin re n sunkun bee ni awon ore re ti n gbiyanju lati tu u ninu. Jesu naa sunkun.



Jesu jade pelu awon eniyan lo si iboji a si gbe okuta le enu re.



"E gbe okuta naa kuro" Jesu pase fun. Marta arabinrin Lasaru si dahun wi pe "Oluwa o ti n run nisinsin yii nitori pe o di ijo merin ti o ti ku."





Jesu pase ki awon eniyan gbe okuta naa kuro leyin naa Jesu gbadura si Baba re ni orun. Jesu fe se ise iyanu nla ti awon eniyan yoo fi mo pe Olorun lo ran-an. Jesu kigbe pe. "Lasaru jade wa" awon eniyan si bere si ni wo inu iho ile tiyanu tiyanu. Se Jesu le so oku di alaaye bi?


Beeni Lasaru jade wa lati inu iho ile ti won de ni aso oku-O wa laaye.

E tu u sile je ki o maa lo.  Kin ni ayo ti o wa nibe!  Ibanuje pada di erin.  Jesu pa oro re mo.  Lasaru di alaye pada omo Olorun nikan lo le so oku di aaye.



Opolopo eniyan ti won ri ise iyanu yii gba Jesu gbo sugbon awon elomiran ninu won royin re fun awon ota re- Awon Olori tempili nitori ilara won gbimo lati pa Jesu, nigba ti Jesu mo eyi O lo kuro nibe fun igba die.



# Jesu ati Lasaru

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Johanu ori kokanla

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje


Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun
iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe:
Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.